# IMỌRAN IYEBIYE FUN AWỌN ONIGBAGBỌ́

**Romu 13:1-14; 14:1-23; 15:1-33**

**ẸKỌ 388 – FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Nitori kò si ẹnikan ninu wa ti o wà lãye fun ara rẹ̀, kò si si ẹniti o nkú fun ara rẹ̀" (Romu 14:7).**

### Onigbagbọ́

Ṣaaju ohun gbogbo, ẹ jẹ ki a ṣalaye ẹni ti a n pè ni Onigbagbọ́. Iwe atumọ ede sọ fun wa pe eyi ni ẹni ti o gbagbọ́. . . . . ninu Jesu Kristi ati otitọ gẹgẹ bi O ti kọ́ ni. A maa n pe Apapọ Orilẹ-ède Amẹrika ni Orilẹ-ède Igbagbọ́, ṣugbọn o daju gbangba pe ki i ṣe olukuluku ẹni ti o wà ni ilẹ yii ni Onigbagbọ́. Onigbagbọ́ ni ẹni ti o jọ Kristi o si tọ fun un lati gbé igbesi-ayé rẹ̀ bi o ti tọ fun Onigbagbọ́ lati ṣe. Yoo dabi Kristi ni iwà, ninu ẹmi, ati ni ṣe.

Ni Antioku ni a kọkọ pe awọn ọmọ ẹyin ni "Kristiani," lẹyin ti Jesu ti goke lọ si Ọrun. Ninu "Ilọsiwaju Ero Mimọ" lati ọwọ Bunyan, a pe akikanju ti o wà ninu itan naa ni "Kristiani," a si ranti pe oun ni ẹni ti o ri ara rẹ̀ pe oun n ru ẹru wuwo; ṣugbọn nigba ti o beere, "ki ni emi yio ṣe lati là?" ẹni kan ti a n pe ni "Onihinrere" tọ ọ si ọna lati tẹle imọlẹ kan ti n tàn ni ọna jijin rere. A sọ fun un pe ki o "Tẹ oju rẹ̀ mọ imọlẹ ni" ati pe lai si aniani yoo dé "ẹnu ọna kekere" kan. Awọn ẹbi rẹ̀ bẹrẹ si i ké tọ ọ lẹyin bi o ti n jade lọ, ṣugbọn Kristiani "fi ika rẹ̀ di eti rẹ̀, o si tẹra mọ́ ire i sá, o n ké, Iye! Iye! Iye ainipẹkun!"

Iye ainipẹkun ni ilepa olukuluku ẹni ti a n pè ni Kristiani. Nitori idi eyi ni a ṣe gbọdọ maa kiyesi ayé wa ati iwa wa lojoojumọ --- a ko fẹ sọ opin ire ije wa nù. Nitori eyi ni Paulu fi kọ awọn ori iwe wọnyii ti o kun fun ẹkọ ti a ṣalaye rẹ̀ yekeyeke fun awọn eniyan ti o wà ni akoko ti rẹ̀ ati fun awa naa pẹlu.

### Bi A Ṣe Le Di Onigbagbọ́

Idakeji ẹni ti a n pe ni Onigbagbọ́ ni ẹlẹṣẹ. Nigba ti ẹlẹṣẹ ba ni igbọgbẹ ọkan fun ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ti o si mọ̀ pe ẹlẹbi ni oun, ọkan ti o ti sọnu niwaju Ọlọrun, o ni lati ronupiwada awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀, ki o si jẹwọ wọn fun Ọlọrun. Ọlọrun ni "oluṣẹsan fun awọn ti o fi ara balẹ wá a" (Heberu 11:6). "Ẹjẹ Jesu Kristi ọmọ rẹ̀ ni nwẹ̀ wa nù kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johannu 1:7).

### Imọran Paulu

Nisisiyii ti a ti mọ ẹni ti a n pè ni Onigbagbọ́, ati bi a ṣe le di Onigbagbọ́, ẹ jẹ ki a ṣe aṣaro lori awọn ẹkọ ti o wà ninu ori iwe wọnyii. Igbọran jẹ́ ọ̀kan ninu akọkọ ṣe iṣẹ Onigbagbọ́ -- awọn ọmọde ni lati gbọran si aṣẹ awọn obi wọn, awọn olukọ wọn, awọn olori ile ẹkọ, ati awọn alabojuto wọn afi bi aṣẹ naa ba lodi si Ọrọ Ọlọrun. Gbogbo eniyan gbọdọ gbọran si aṣẹ awọn ọlọpa ki a si fun wọn ni ọ̀wọ̀ ti o tọ́. Awọn ofin ti a ṣe fun lilo oju titi wà fun aabo awọn ara ilu, o si tọ́ lati pa wọ́n mọ́ kinnikinni, paapaa awọn ti o jẹ́ Onigbagbọ́.

"Ẹ máṣe jẹ ẹnikẹni ni gbese ohun kan, bikoṣepe ki a fẹran ọmọnikeji ẹni" – igbese ti a ni lati maa san nigba gbogbo. Ifẹ a maa ni inu didun lati tẹnilọrun; oun a tilẹ maa fiyesi ọna ti oun le gbà jẹ iranlọwọ fun awọn ẹlomiran ati lati mu inu wọn dùn. Lati mọọmọ pa ọmọnikeji ẹni lara jẹ iwa ẹlẹṣẹ, ki i ṣe ti Onigbagbọ́ rara. Owu, ijà, ati ikoro ọkan si ẹnikeji jẹ eso ikorira, ki i ṣe eso ti ifẹ. "Ifẹ ki iṣe ohun buburu si ọmọnikeji rẹ̀." Ọmọkunrin tabi ọmọbinrin ti o ba n jowu ọdọmọde miiran nitori awọn anfaani ti o ni ninu Ihinrere, ninu lilo ohun-elo orin tabi ninu orin kikọ, ni lati wá ọkàn ara rẹ̀ ri ki o si bẹ Ọlọrun fun idariji.

### Ohun ti o Ṣe Pataki Ju Lọ

Awọn miiran ninu awọn Ju, nigba ti Kristi wà ni ayé, a maa ṣe ọfin toto nipa ohun ti wọn n jẹ, wọn a si maa ri wi si awọn ti ki i ṣe ọfin toto bi ti wọn. Lode oni paapaa awọn ẹlẹsin miiran wà ti wọn maa n ka eewọ fun awọn eniyan nipa ẹran jijẹ tabi iru onjẹ miiran. Ṣugbọn Jesu kọ́ wa pe: "Ki iṣe ohun ti o wọ ni li ẹnu lọ, ni isọ enia di alaimọ́, bikoṣe eyi ti o ti ẹnu jade wá, eyini ni isọ enia di alaimọ́" (Matteu 15:11). "Nitori lati inu, lati inu ọkàn enia ni iro buburu ti ijade wá, panṣaga, agbere, ipania, ole, ojukokoro, iwabuburu, itanjẹ, wọ̀bia, oju buburu, isọrọ odi, igberaga, iwere: lati inu wá ni gbogbo nkan buburu wọnyi ti ijade, nwọn a si sọ enia di alaimọ́" (Marku 7:21-23). Nipa bẹẹ a kọ́ ẹkọ lati inu eyi pe awọn ọrọ ti a n sọ ati igbesi-ayé ti a n gbé ṣe pataki pupọpupọ. Ẹ jẹ ki a pa àya wa mọ "jù gbogbo ohun ipamọ́, nitoripe lati inu rẹ̀ wá ni orisun iye" (Owe 4:23).

### Wiwa ni Imurasilẹ

Paulu sọ fun awọn eniyan ti akoko ti rẹ̀ pe òru ibi fun ayé yii fẹrẹ kọja; ọjọ iṣẹgun fẹrẹ de. Wo o bi o ti sun mọ wa to ọjọ oni! "Ẹ jẹ ki a bọ́ ara iṣẹ okunkun silẹ, ki a si gbé ihamọra imọlẹ wọ̀." A ṣe apejuwe

“ihamọra” naa ninu Efesu Ori 6, awọn ohun ihamọra naa ni a si darukọ gẹgẹ bi Otitọ, Ododo, Alaafia, Igbagbọ́, Igbala, ati ida Ẹmi ti i ṣe Ọrọ Ọlọrun.

“Gbogbo wa ni yio sá duro niwaju itẹ́ idajọ Kristi.” “Olukuluku wa ni yio jihin ara rẹ̀ fun Ọlọrun.” Nitori naa ko tọ fun wa lati yan ipo Onidajọ ori awọn ẹlomiran. Onigbagbọ́ kan le ṣe alailera ju Onigbagbọ́ miiran lọ; boya igbagbọ ti o ni ko lagbara to lati bori awọn iṣoro keekeekee. A n sọ fun awọn ti o lagbara ninu igbagbọ pe ki wọn “mã ru ẹrù ailera awọn alailera,” ki si i ṣe lati maa ṣe ohun ti o wu ara wọn. Kristi ku fun gbogbo eniyan, ani fun arakunrin ti o tilẹ jẹ otoṣi ati alailera ju lọ, a ko si le fi ẹnu sọ bi ẹmi rẹ̀ ti ṣe iyebiye to. “Kristi pẹlu kò ṣe ohun ti o wù ara rẹ̀” (Romu 15:3). Nitori naa bi ẹnikẹni ba n ṣiyemeji ninu ọkan rẹ lori ohun kan ti o n fẹ lati ṣe pe boya o le jẹ ikọsẹ fun ẹlomiran, o yẹ ki o fi ohun naa silẹ lai ṣe. O ni lati beere lọwọ ara rẹ̀, “iru iṣẹ wo ni eyi yoo ṣe ninu ọkàn arakunrin mi?” Ẹnikẹni ko gbọdọ wi bi Kaini ti o sọ pe, “Emi iṣe olutọju arakunrin mi bi?” Olukuluku ni lati sa gbogbo ipa rẹ̀ lati ran arakunrin rẹ̀ lọwọ lati jogun iye ainipẹkun.

**“Awọn Onigbagbọ́ Aabọ̀”**

Ọpọlọpọ eniyan ni o wa laye lọjọ oni ti wọn ni itara fun Oluwa. Wọn le kun fun aáyan ninu iṣẹ ile-isin, wọn ṣe tan lati sẹ ara wọn, wọn le maa gbe igbesi aye iwa rere. Ṣugbọn ayafi bi eniyan ba ni ifẹ Ọlọrun tootọ ninu ọkan rẹ̀ -- ifẹ si Ọlọrun ati ifẹ si arakunrin rẹ̀ -- o kuna lati de odiwọn Onigbagbọ́. Awọn miiran le fẹ ọla ati iyin awọn eniyan ju ẹmi awọn eniyan lọ. John Wesley pe iru awọn eniyan bẹẹ ni “Onigbagbọ́ aabọ̀,” ṣugbọn otitọ ibẹ ni pe, ọkan ninu meji ni eniyan ni lati jẹ: “Onigbagbọ́ tabi ẹlẹṣẹ.”

Ẹ jẹ ki awa ti a n jẹ orukọ “Onigbagbọ” maa ranti nigba gbogbo pe Onigbagbọ gbọdọ dabi Kristi. O gbọdọ jẹ adura ati ilepa wa lojoojumọ lati le dabi Kristi ninu ohukohun ti a n ṣe tabi ti a n sọ.

## AWỌN IBEERE

1 Sọ itumọ ọrọ ti a n pe ni “Onigbagbọ.”

2 Iru igbesi-ayé wo ni Onigbagbọ maa n gbé?

3 Ki ni imọran Paulu fun awọn Onigbagbọ́ nipa ifẹ?

4 Bawo ni ayé ṣẹ le mọ iyatọ laaarin Onigbagbọ ati ẹlẹṣẹ?

5 Lati ibo ni ero buburu, igberaga, ẹtan, iwa-buburu ti n wá?

6 Ki ni ṣe ti o jẹ ohun pataki lati maa ka Ọrọ Ọlọrun ati lati maa gbadura?

7 Ki ni itumọ “ihamọra”?

8 Ki ni Paulu sọ nipa ṣiṣe idajọ ẹlomiran?

9 Ki ni opin olukuluku Onigbagbọ́?